To The Chief Secretary to the Governm[ent]



# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD

VOL. V. NO. 258 SATURDAY, JANUARY 21, 1928 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.




## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

## EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi latlat ati litun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lowo lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Eda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san iawotan patapata, I o si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.

"AWA O MA JO, AWA O MA YO, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimo, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—
No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

**Coffins to suit your Taste**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you No worry, prompt attendance Make a call.

# Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-okọ, Iso lorisirisi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorisirisi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọsan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa Pokun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street. (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimora. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.

**Are you a Mechanic ?—If so you must want Tools, now or soon**

**Do you intend to put up a house ?—**
Then you will require Builder's Hardware

In either case you cannot do better than call at

## B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

## J. C. VAUGHAN

Ti ile-ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna: bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ o ni'ya lati ra nibẹ:

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna.

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atan Ajanaku lọjọ to ti pẹ: bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai! bi o ri orişirişi Ok ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo oja meremerejibe.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | [illegible] |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

B'O R'AJA EWULỌ O MA KI I.

Ori lo yọ ọkọnrin kan ara Oṣogbo ti "Ọmọ Jaguda" kan fẹrẹ pa ni aparọ ni Banki nla ni (B.B W.A.) ni Ẹhingbẹti lọsẹ to koja nipa yiyọ adọjọ pọnun ni apo rẹ gẹrẹ bi o ti gb'owo na tan ni Banki na; a gbọ pe bi Ọgbẹni yi ti fi gbogbo owo yi ti o jẹ okuru *paper* si apo, bẹni ọmọ Jaguda yi nṣọ ọ, bi o si ti naka lati yọ lapo ọkọnrin yi, bẹni ọkọnrin na lọ igbe gbẹ ẹ, afara ko si, awọn ti o wa nibẹ ko igbati igbamu bo Afa'mọ-lori iyagbẹ yi, nigbati nwọn si jaja fi silẹ, be lo ṣiyan ti ko duro gba ọbẹ nipa sisare tobẹ ti atẹlẹsẹ rẹ fẹrẹ le ma kan ni ipakọ.

IBOSI ALUBA L'ODE ONDO.

Ihin kan ni lọsẹ yi pe ọgọrọ awọn ọdọ l'ọkọnrin l'obinrin lo nku pi bi ina ni ilu Ode Ondo ni lọlọyi, ki lo mu irufẹ sababi bayi wa? Ẹnyin Ijọba, ẹ wo kan ṣe o, ki ọrọ na to gb'ọwọ.

OGUN OYINBO, TO TO FUN U !!!

Gbake ni a gbọ pe ina bẹlẹjẹ kan ṣẹlẹ ni Ile Ifi-iwe ṣọwọ si 'dalẹ (*General Post Office*) ti Eko nibi ni lọlọyi; nigbati a si fi 'mu finlẹ lati mọ kilo b'oyun b'okọnrin, eyini ni pe kini ina ṣe r'aye wọ ibẹ, a gbọ pe ninu ogun ti awọn Ẹgbẹ ti o nta ogun Oyinbo (*West African Drug Co.,*) ti apa ile Lọya Alakija kekere fi ṣọwọ si idalẹ ni ọkan ti gbija ti o si la'na; Ijọba ti pe awọn Ẹgbẹ Oyinbo na lẹjọ ọdaran si Kotu Ọlọpa nisisiyi.

EYI NKỌ! OLE TO JI IBỌN GBE!!!

Irohin titakiji kan kan ni pe ni ọsẹ diẹ sẹhin awọn ole ko ibọn ti o to mẹrin ti Kiriyo ọkọnrin kọkọ-bọtọ kan fi s'abẹ irọri rẹ sun ile nile rẹ ni idi-oro fun idabobo ara rẹ nitori awọn "onisẹ oru" wọnyi.

Nigbati enia fi ibọn rọri fun gbigba ara rẹ lọwọ awọn Barao, ti awọn ole wọnyi kanna si gboju gbaiya ji ibọn na lọ, ẹ ko ṣai mọ wipe ọrọ yi p'esi jẹ nigbana ara 'bi?

OṢE, IGIDA! COKER ỌMỌ AJỌBO, Ẹ KU AGBA.

Anu ṣe ni gidigidi lati ri pe bakanna ni awọn Adajọ mẹta ti Kotu Apili ti a ṣe koja l'Eko nibi laipẹ yi, da ẹjọ Ọgbeni J. K. Coker nipa labari ọran rẹ pẹlu Alake Ademọla, a si ni ki o tun san pọnun mẹwa owo irin-ẹsẹ.

---

## AJỌ-IGBIMỌ DẸMỌ

LATI ỌWỌ KEKERE- AWO.

Si Oniwe-irohin "Eko Akete,"

Mo bẹrẹ foji o,

Labari ti a kọkọ gbọ nipa Ẹgbẹ Dẹmọ ni ajọ ti nwọn ṣe lojọ Alami ni yara Igbimọ (*Committee Room*) ni ile Afari-ogun ni Ẹhingbẹti ni wipe nwọn je oye titun ti ẹgbẹ "*Annual election of the officers*" eyiti ao fihan nyin ni isalẹ yi gẹgẹbi a ti gbọ ripọti na si, ki a to wa ni anfani lati rohin iṣẹ ribiribi ti awọn ẹgbẹ Bombata yi ṣe lọjọ Satide ijẹjọ ti nṣe ọjọ 14 oṣu yi.

Ni ede ti oyinbo ni nwọn ṣe ripoti na fun wa, a si ro wipe irufẹ ede oyinbo ti nwọn fi ṣe yiyan oye titun na ko le tobẹ ti a fi le ni a nṣe ayan lati yi wọn si ede ti Yoruba, ati pẹlu aye ha fun wa diẹ lọsẹ yi lati ṣe wosika gbọrọ-gbọrọ eyiti a tun ṣeṣe dawọle lati ma ṣe lati ẹnu ọjọ mẹta yi wa.

Gẹgẹbi awọn ripọti yiyan oye titun na tilọ ni iwọnyi :—

Hon. Dr. John Akilade Caulcribk (the third Lagos member) a Vice-President of the Demo-

cratic Party was elected to succeed the late Mr Joseph Egerton Shyngle as member of the Executive Committee which consists of seven members.

The Honourable Eric O. Moore (the First Lagos member) a Vice-President of the Party, Mr I. Adebayọ Doherty, and Mr. Isaac Kushika Robber's were unanimousley re-elected the Treasurer, Mr Thomas Horatio Jackson, Editor and Proprietor of the Lagos Weekly Record" remains the Honarary Secretary of the Party, Revd. J. R. Williams and Messrs I. Ibaru and George I. Phillips as Assistant Secretaries.

The organising Secretaries for 1928 are Messrs. F. G. R. Leigh, A. O. Cole, James Bailey, Lemomu Lawani, Lemọmu Ọba (Okunu) and Musa Bashorun the Executive Committee Members were re-elected for the Year 1928.

Mr I. Adebayọ Doherty a Vice-President of the Party, remains Secretary of the Board of Finance.

Gẹgẹbi ọran oye titun ti ipade Komiti Dẹmọ lọjọ Alamisi ọjọ 12 oṣu yi tilọ ni iyẹn o. Ẹ jẹki a wa ṣe adura fun awọn ẹni wọnyi ti nwọn gba irufẹ ọla bayi fun wọn pe ki Ọlọrun Ọba ti ki si lẹhin alabosi ma ṣai jẹki oye wọn [illegible] kalẹ ki Ọlọrun Ọba na [illegible] na mọ wọn lori lọwọ wọn, ki o si [illegible] si gba iyi wọn kuro luku wọn [illegible] jẹki ajinde ara ma jẹ fun oluku[illegible] ati asiki anfani fun ile ati ọna wọn—aṣẹ [illegible]ẹm ki o ri.

## AJỌ GBOGBO-GBO TI ẸGBẸ BOMBATA ẸGBẸ-DẸMỌ.

Ni Satide ọjọ 14 oṣu yi ni nwọn ṣe ipade gbogbogbo ni ile Afari-ogun (*Glover Memorial Hall*) lẹhinugbẹti lati iwọn agogo mẹrin labẹ Alaga ẹgbẹ na Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi-Jones.

Ipade yi bẹrẹ ni agogo marun ni ikawọ awọn ẹni Ọla wọnyi, Ọlọla Dokita J. A. Caulcrick, Ọlọla Lọya Eric O. Moore, oloye Eletu Odibo, oloye Oluwa, Oloye Olumẹgbọn, Abagbọn Aṣọgbọn ati Saka Oṣodi, Ọgbẹni F. Leigh, Ọgbẹni Herbert Macauley ati awọn Ratibi gbogbo pẹlu awọn jakanjakan.

Lẹhinna a tun ri awọn alejo omiran bi Lọya Ọlatunde Vincent ati Lọya Kuṣemọ Sholuade.

Nigbati ajọ yi bẹrẹ ni agogo marun gan lati owọ Ọlọla Dokita J. A. Caulcrick, o ka gbogbo ohun ti ẹgbẹ fẹ ṣe ni ipade si eti igbọ awọn ọmọ ẹgbẹ gẹgẹbi awọn ohun ti nwọn fi sinu iwe ikede.
Awa ṣe akiyesi wipe ohun mẹjọ ni nwọn fi sinu iwe ikede (*Notice*) pe nwọn yio ṣe eyiti olukuluku ti ni ero pe awọn yio gbọ ni ayọ, ṣugbọn ninu awọn ohun ti nwọn sọ awọn yio ṣe idaji ni nwọn ṣe nibẹ.

Ekini ni ti ọran iwe-ẹbẹ ti ẹgbẹ na sọ wipe awọn yio ṣe si Ọga awọn Gomina (*Secretary of State*) onikoyi-oko, ekeji ni ti riran awọn ikọ lọ si ọdọ Ọlọla Gomina Graeme Thomson, olubori rẹ ni ti ọran owo-ajulọ tabi owo-ere (*Income Tax*) eyiti Ọgbẹni Makọli fi ẹnu rẹ ṣe iṣẹ nla pataki sidi ọran yi lọjọ na, nwọn tun wa yan ti ọran ẹjọ Olowo Eṣugbayi Eleko ti o mbẹ ni Privi-kan-sulu ibiti a mọ ni gbangba dẹkun.

Ọlọla Dokita Caulcrick sọfun awọn ọmọ ẹgbẹ wipe on gbe awọn iṣẹ ribiribi wọnyi le Ọgbẹni Makọli lọwọ lati ṣe o joko.

Ọgbẹni Herbert Macaulay dide o ki gbogbō ọmọ ẹgbẹ pe awọn ku ijoko, gbogbo wọn si fi ifẹ ọkan nla wọn ti nwọn ni si dalohuu pẹlu ayọ ati ariwo nla; eyiti tilẹ fihan wa wipe ifẹ pataki ti nwọn ni si Makọli tubọ ngbilẹ siwaju si lọkan awọn ara ilẹ yi papa awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ. Makọli bẹrẹ ọrọ rẹ wipe iṣẹ ti awọn wa ṣe loni ni iṣẹ ọran owo ajulọ, lori eyi lo sọ wipe *Income Tax* yi nitotọ nwọn nsan ni ilu Oyinbo, ṣugbọn ki nwọn to bẹrẹ si san ni pataki ogun la nmu wọn san ni ilu oyinbo ri, fun iranlọwọ, ogun bi iru eyiti ara ilẹ yi ṣe fun Ijọba Igẹsi laseko ogun Ajakaiye nigbati Ijọba fi ni ki awọn ara ilẹ yi ṣe iranlọwọ bi [illegible] ẹgbẹrun ọna mẹdogun Ponun fun wọn ti awọn ara ilẹ yi si fi itara ati ifẹ ti nwọn ni si Ijọba Igẹsi gẹgẹbi alakoso wa fi di owo na.

Ṣugbọn ogun ọdun si igba yi ni nwọn bẹrẹsi san owo *Income Tax* yi ni pataki, eyiti awọn Ijọba fẹ mu wa ni agbara lati san nihin, o sọrọ pupọ lori ọrọ yi, bi o ti jẹ wipe nigbati Ijọba nlẹ gba owo ile lọwọ awọn ara ilu Saro ti awọn ara ilu Saro si fi ake kori ni aseko Gomina Ọlọla Frederick Cardew ni nkan bi ọdun 1899 ti ọran owo na si mu akatakiti dani, lẹhin igbati Gomina ilu na nsọ wipe li aseko ti rukerudo yi yio fi ṣẹlẹ on mbẹ ni ilu Oyinbo larin oṣu mẹfa rẹ.

O si nsọ wipe awọn ko fẹ ki ti ọran owo yi ri bayi fun wa nihin, nitoripe ninu oṣu August ọjọ 23 1927, ti nwọn ṣe Igbimọ Aṣofin ilu (*Legislative Council*) Ọlọla F. M. Baddeley lo mbẹ ni Adele Gomina Graeme Thomson, nitoripe on papa mbẹ ni ilu oyinbo, ti nwọn fi so ofin na nigba yi nipa ibo ti nwọn di eyiti awọn ẹniti o fẹ lo pọ ju awọn ẹniti ko fẹ lọ papa bi o ti jẹ wipe gbogbo oyinbo ti o mbẹ ninu awọn ẹniti o fi owọ sọ'iya pe ofin owo na tẹ awọn lọrun, onişẹ Ọba ni gbogbo wọn, nipa yi awọn ko fẹ ki oran na dabi ti awọn ara ilu Saro, boya Gomina Graeme Thomson le sọ wipe ṣe on ko si nihin li aseko yi nitorina bi awọn yio tişe fẹ lati ṣe iwẹ-ẹbẹ si i, iwe ẹbẹ na ki iṣe iwe titako Ijọba bẹni ki isi iṣe iwe titakanrangban pẹlu, iwe ọwọ ati irẹlẹ ti awọn fẹ ṣe si Ṣẹkiteri agba ti ilu Ọba, eyiti awọn yio fi ṣọwọ si Ijọba nihin lati ba awọn fi ṣọwo sọhun. Ọlọla Dokita Caulcrick dide lẹhin ti Ọgbẹni Makọli sọrọ diẹ lori ọran yi tan. O si kọ si awọn ọmọ ẹgbẹ gẹgẹbi Alaga wipe iwe ẹbẹ na on fẹ ki Makọli ka si eti

igbọ janma lati jẹ ki o ye gbogbo awọn ẹniti o ba tọ suna fun lati fi iwe-ẹbẹ na ṣọwọ, o si sọ wipe inu on yio dun lati ri ọwọ awọn ẹniti iwe ẹbẹ na ba dun mọ pe ki awọn fi ranṣẹ, gbogbo ọmọ ẹgbẹ patapata ani gbogbo awọn ẹniti o mbẹ ni ajọ yi fi itara ati igbona ara na ọwọ wọn si oke fun ami ẹdun ọkan ati ariwo ogunlọgọ enia wipe awọn lọwọ si iwe ẹbẹ na pe ki awọn olotu ẹgbẹ fi ṣọwọ, lẹhin ti nwọn ṣe bayi tan.

Ọlọla Dokita Caulcrick si tun bere lọwọ janma wipe ẹniti ko ba fẹ ki awọn fi iwe-ẹbẹ na ṣọwọ si ọga awọn Gomina ni ilu Ọba lati ba wọn da ofin owo na ro ki awọn oluwarẹ na ọwọ wọn si oke lai fi itiju k'arun, oju wa da lati ri wipe ẹda Ọlọrun kan ko ṣẹṣẹ run'ra debi ti ao fi ri ẹnikan si ika rẹ firi lasan lai tilẹ ti na si oke, awọn obinrin ẹgbẹ lasan ni yio fẹrẹ ie ya oluwarẹ jẹ ni tutu, biọ ran yi ti jẹ ohun ti o ka wọn lara to, ki a sa kuku sọ wipe kosi ẹniti o na ọwọ si oke, Ọlọla Dokita Caulcrick sọ wipe on fun Ọgbẹni Makọli laṣẹ ne ki o ka iwe-ẹbẹ na si eti igbọ janma.

Makọli dide lati ka iwe yi, gẹgẹbi iwe na ti gun to, o sọ wipe awọn ki yio ka ni ede ti oyinbo, o mu iwe ẹbẹ yi o ka fun ọmọ ẹgbẹ ni Yoruba yekeyeke gẹgẹbi ohun ti awọn olotu ẹgbẹ yi tẹ sinu iwe na, o si sọ wipe kosi ọrọ kan ti o jọ bi ẹnipe awọn fi se oju gangan sinu iwe ẹbẹ na, bikoṣe ọran irẹlẹ bi igbati ọmọ nfẹ tọrọ ohun lọwọ baba rẹ.

O si sọ wipe ẹgbẹrun meji ni ni iwe na ti awọn yio tẹ, bi Ọgbẹni Jackson (akọwe ẹgbẹ) ti o ntẹ iwe na ba pari rẹ, awọn yio ṣe paramu lati jẹki oluwarẹ ri kulekule iwe na lori ohun ti awọn fi sinu rẹ ti awọn si tumọ fun nyin ni ede yoruba nisisiyi.

O mu ẹnu kan ọran awọn ara ilu Aboh nipa rukerudo ti ọran owo-ori yi fẹ bi silu wọn nigbati District officer ti Abraka fi sọ wipe awọn ara ilu yi yio ma san ṣile mẹwa owo-ori, o ni ni ọjọ kan awọn ara ilu na lọ si ile ojoye wọn kan oloye ti nwọn npe ni Arumana gẹgẹbi awọn ti ni Idẹjo, Abagbọn, Ọgalade ati Akaribgbo bẹ-bẹ nihin bẹ lo wa fun awọn ẹlomiran na nibomiran.

Oloye Arumana yi ni nwọn lọ pẹjọ si ile rẹ, awọn ẹni pataki ti o mbẹ ni apejọ na oruko wọn njẹ Enebeli, Enwulu ati Odua, gbogbo awọn wonyi mbẹ labẹ D. O. (Abraka) ilu awọn jẹ Igbereko ilu Warri.

Nigbati nwọn da ọran owo-ori silẹ nibẹ, gbogbo awọn ara ilu yi sọ wipe awọn ko ni agbara lati sanwo yi, awọn nsanwo Kotu Ibilẹ ati awọn pẹpẹpẹ 'miran dede, awọn ko lagbara owo-ori lati san nitorina ki odua ba wọn lọ sọfun D. O. pe ki o sọfun Aṣoju ilu Warri ( *Resident for Warri*) pe awọn ki yio le san owo ti nwọn nfẹ gba yi arara, nwọn ṣe akatakiti ọran yi ni ile oloye Aramuna. O ni nwọn sọ wipe Akọwe Kotu kan ti o mbẹ nibẹ lọjọ na oruko rẹ njẹ Aduwaye awọn ro wipe o lọ sọfun D. O. ati Ọba wọn ti o njẹ Obi-opute, Ọba wọn na lẹhin Ijọba lo duro si girigiri, Akọwe Kotu na si nlọ sọ ohun ti oju rẹ to ati oju rẹ ko to fun D. O. wipe bayi bayi ma ni awọn ara ilu Aboh nwi, eyi dabi ẹni nwa oju're kiri.

O ni lẹhin oṣu meji rẹ, nwọn lọ si Kotu D. O. (Abraka ) mbẹ nibẹ, nwọn si fi nhan D. O. nibẹ lọjọ na wipe gbogbo nkan ni Ijọba ngba owo lọwọ nwọn fun, bi nwọn ba ge ọpẹ kan loko awọn Ijọba yio gba £5 lọwọ nwọn bi awọn ba ge igi Iroko Ponun mẹwa li awọn yio san, bẹni nwọn ngba owo lori ọkọ ti nwọn nkan, bi ẹnikan ba gba aya ẹnikan mọ ẹnikan lọwọ, bi ọran bi ogun Kotu Ijọba yio gba Pọnun marun lọwọ ẹniti o gba aya, nwọn ko si ni san pada fun ẹniti aya rẹ kọ silẹ, apo Ijọba ni Pọnun marun na nlọ.

Bẹni iru iṣẹ pe, ki awọn obinrin ara ilu Aboh yi lọ ge igi ni'gbo ti yio fi da ina fun awọn oyinbo onișẹ-Ọba, tabi awọn Akọwe Kotu ati awọn iranṣẹ Kotu, lai jẹ wipe Ijọba san kọbọ aladọjọ fun wọn lori iṣẹ nla tamtam yi, oṣoṣu si ni awọn nṣiṣẹ ipa yi.

Nigbakugba nwọn yio mu ọkọ nwọn a fi mu awọn Akọwe Kotu lọ si ilu wọnyi :—Ọpari Umoru Utshi, Ganagana ati Araba lai jẹ wipe nwọn san fadini fun wọn, alalikuwa awon lo ọko ki iṣe wipẹ nwọn nyi wọn ni ọwẹ lọ si awọn ibiti a darukọ pe nwọn nko awọn oṣiṣẹ Kotu lọ nigbagbogbo yi.

Bẹni Ọba Obi-Opute yio paṣẹ fun awọn obinrin ilu pe ki wọn ma lọ pa ile awọn Oṣiṣẹ Kotu ati ile awọn iranṣẹ Kotu, nwọn ki yio san okan fun wọn.

Awọn ara ilu patapata nwọn yio jade lai ku ẹsẹ kan lẹhin ti kekere ti agba, awkn yio lọ tun kna ṣe lati ilu nwọn Aboh lọ de ilu Ashaka, Otagba, Efo, Osia, Ekoku, Gbedeyi, Obirokọ, ati titi lọ de ilu Abraka nibiti D. O. gbe wa, gbogbo ọna wonyi ni Moto nrin, lai jẹ wipe nwọn ri Kọbọ gba nidi rẹ ṣugbọn nwọn ko mọ bi awọn ojoye wọn ngba owo-ọya wonyi lọwọ Ijọba bi nwọn ko si ngba owo kan, ṣugbọn o da awọn loju wipe awọn ki ngba ọkan lọwọ Ijọba lori iṣẹ aṣegan ti awọn sọ wipe awọn nṣe na, oṣu mẹta-mẹta ni awọn si nṣe iṣẹ ipa yi. Nwọn wa nbi D. O. lere wipe lori gbogbo wahala ti nwọn nṣe yi, ti o jẹ wipe kosi aye fun wọn lati lọ ṣiṣẹ bi awọn yio tiṣe jẹun lasan, ọna wo ni awọn yio gba lati ma fi san owo-ori ti Ijọba nfẹ gba? Ki o sọ fun awọn ki awọn gbe.

Oyinbo D. O. na si sọ fun wọn wipe ki nwọn lọ ṣe ṣawura lori rẹ ki on to wa ba wọn.

Kotu Ibilẹ bi mejila ni nwọn sọ wipe nwọn ni, orukọ wọn ni eyi :—Aboh, Ashaka, Obiaruku, Muwelu, Effo, Abara, Otaba, Utshi, Oshisha,

Orogu, Ogrmeh gbogbo awọn Kotu yi pẹlu Abraka ọkan na ni, gbogbo Kotu yi si ngba owo lọwọ wọn nwọn sọ wipe ọna wo ni awọn yio gba lati ma ri owo-ori san pẹlu?

O ni nwọn sọ wipe ipada kan ti nwọn tu ṣe Akọwe Kotu kan ti o njẹ Aduwaye ni ki nwọn wa ra Arumona ati Esumaya mu wipe awọn lo nkọ awọn enia pe ki nwọn ma takanrangba si ọran owo-ori na, nwọn lọti awọn ẹni meji yi mọle nibiti awọn Ọlọpa gbe wa.

O ni nigbati awọn ara Aboh yi wo sa ti nwọn ko ri oye kan, gbogbo lọkunrin ati obinrin pe ara wọn jọ larin oṣu December to kọja yi, nwọn lo fọ ilẹkun, nwọn si yọ awọn ẹni meji ti nwọn ti mọle na lẹhin eyi ni Akọwe Kotu ibẹ ranṣẹ lọ si ilu Warri pe nwọn ma ti ṣe jamba si gbogbo Kotu. Ọgbẹni Makọli rohin pupọ lori ọran yi pe bi awọn ti gbọ ọran na si ni nyẹn. O ni ni lẹloyi awọn gbọ wipe nwọn mu awọn bi ogoji ni ilu Aboh, nwọn si fi wọn si ẹwọn, awọn ara ilu na si ranṣẹ si awọn wipe ki on ba wọn ṣe iwe-ẹbẹ si Ijọba lati da wọn silẹ, ni ẹhin rẹ ni on ngbọ wipe on fẹ gba owo lọwọ awọn ara ilu yi lati ba wọn ṣe iwe-ẹbẹ o si da on loju wipe bi o ba ṣe wipe owo ni on ngba lọwọ awọn enia on yio ti kọ pẹtẹsi mẹfa, on nja fun ore ilu on ni, on ko si kọ lati gbe ẹmi on ta sidi rere ilu on, gbogbo ọmọ-ẹgbẹ fi igbona ara sọ lẹsẹkanna Ọlọrun ko ni jẹ, o si tun nsọ wipe ile ti on ki iṣe ile ọtẹ, kosi ohun bonkẹlẹ kan ti on nṣe nibẹ, bi nwọn ba fẹ, nwọn le ma wa sun ni ile on lati ri aṣiri ohun ti on nṣe nibẹ, on ni to yara mẹta ti on le fi enia si, o ni nigbati on tigbọ wipe nwọn ni on nfẹ gba owo jẹ lati fi ba wọn ṣe iwe-ẹbẹ ni on ti sọ wipe on ki yio ṣe mọ-

O sọrọ pupọ nipa ọran owo-ori wipe o yẹ ki a tokere kigbe igi ganganran ma gun ni loju, nitoripe nigbati aseko ti nwọn yio gba owo koi ti de, ti o jẹ wipe ogede wipẹ nwọn ṣi nsọ asọtẹlẹ rẹ, ti o si nmu ijangban wa wa yi, ti o ba wa di aseko ti nwọn yio gba owo-papa nk ọkini awọn mọ wipe yio hu silẹ? Nitoripe bi o ti nbọ kẹrẹkẹrẹ yi, bi yio tiṣe de apa tiwa ni iyẹn.

O rohin bi nwọn tiṣe nipa ogun Adubi, ni ọdun 1918 nigbati nwọn nfẹ gba owo-ori eyiti awọn gbọ wipe ẹgbẹrun mẹta ni awọn ṣọja pa, di bi awọn si ti nsọ yi, awọn koi gbọ kini ohun ti Ijọba ṣe si idi ọran na. Ati pẹlu nigbati o ba ya ni awọn ẹlomiran yio ma lọ tọka fun Ijọba wipe awọn lagbaja awọn tamẹdu ni ko fẹ jẹki nwọn san owo-ori ni ilẹ yi.

O la alaye fun ẹgbẹ wipe ni aseke Ọba Dosumu ti Ijọba Igẹsi fi gba ilẹ yi ni ọdun 1861 oṣu August ọjọ le rẹ, pẹlu ipa ni Dosumu fi gbe ilu fun wọn nipa ti tọwọ bọ iwe ni ile Gomina nigbati Ọba Dosunmu nwo ọkọ ogun (*Man of-war*) ṣanṣan lebute, ti Ijọba Igẹsi si ta Asia si ilẹ yi lọjọ na, eyiti awọn Idẹjọ nfi ọwọ sọiya loni pe awọn ni onilẹ.

Lati igbati Ọba Dosumu si ti gbe ilu yi le Ijọba Igẹsi lọwọ lagbara awọn ko gburo ogun kan ni ilẹ yi debi ti ẹjẹ yio fi ta silẹ, awọn si ngba ladura wipe ki Ọlọrun ma ṣe jẹki awọn ri ohun ti o jọ bẹ ni arin ilẹ yi, o sọrọ pupọ pẹlu itara ọkan. Nigbati o ṣe alaro lori ọran wọnyi tan o wa mu ẹnu kan ọran owo ti nwọn nsan fun ile ẹgbẹ bi o ti jẹ wipe owo na ga pupọ fun wọn lati ma pe ati wipe nigbati awọn mbọ ni ajọ Kọmiti Ijọ Alamisi 12. yi ni awọn ṣe ṣawura lati fi da owo ti awọn yio san, awọn si gbe iwe owo na lọ ba awọn jakanjakan ti o jẹ olotu ẹgbẹ, ki awọn to le ri owo na lati san, o sọ wipe Pọnun kan ati ṣile mẹrin ni awọn ti nsan fun ile ẹgbẹ yi ri, nigbati awọn ṣẹṣẹ bẹrẹ ni 1923, ṣugbọn nisisiyi o ti fo fẹrẹ di Pọnun mẹjọ ati ṣile mẹjọ inu awọn si dun nisisiyi wipe Lọya Moore mbẹ ninu awọn olotu ile-ẹgbẹ yi, awọn yio bẹ wipe ki o ba wọn rin irin lati jẹki owo na buku sẹhin.

Ọlọla Lọya Moore ẹniti o tun gba ipo Alaga ni iwọn Agogo mẹfa ku iṣẹju mẹdogun sọrọ diẹ lori eyiti o mbi awọn ọmọ-ẹgbẹ bere nipa awọn ikọ ti Makọli sọ wipe ẹgbẹ yio ran lọ ba Gomina lati lọ jirẹbẹ nipa owo-ori yi, lẹhinna, o si sọrọ lori ti owo ti ẹgbẹ nsan fun hihaya ile-ẹgbẹ wipe Ijọba ti yan on si ara awọn olotu ile-ẹgbẹ yi, on yio si mura nisisiyi lati sa agbara on lati jẹki owo na buku sẹhin bi eyi ba ṣe'ṣe ni, on kọ gbe ogun rẹ lori pe yio ṣe o, ṣugbọn on ro wipe boya agbara ti on yio sa yio mu'ko.

Ọgbẹni Makọli dide o wa mu ẹnu kan ọran ẹjọ Ọba Eleko eyiti gbogbo ọmọ ẹgbẹ ti nda'tọ mi lati gbọ, wipe ọran na ṣi mbẹ ni niwaju aje nisisiyi o ni, ni ọjọ 11 oṣu yi ni ireti awọn wipe nwọn yio ṣe ẹjọ na, ṣugbọn iwe irohin ilu oyinbo "West Africa" ti ọjọ 24 Dec 1927, sọ wipe awọn gbọ wipe ninu March ti mbọ yi ni ogongo ẹjọ na yio sun'ra ki, on si mọ oyinbo ti o ṣe wosika na sinu iwe-irohin ni ilu Ọba, o si ka wosika oyinbo na bayi pe:—Prince Eleko lcase, it is understood will come before the Privy Council sometime in March. Nitorina atana ma ana kole to ateni meni, ṣugbọn on fẹ ṣe ofofo kan fun nyin, ofofo na ni wipe on ti se ilu kan silẹ, ki Ọlọrun ṣọ wa di igba na; gbogbo ọmọ-ẹgbẹ pa ariwo ge.

Ajọ tuka ni dede agogo meje alẹ na, Adura tiwa ni pe ki Edumare to bi o ti tọ loju Rẹ—aṣẹ dandan gban a.

Emi ni tiyin nitotọ,
KEKERE AWO.

## ỌMỌ OLOWOGBOWO ATI KARETA.

Kareta jẹ on boju-boju ti awọn Oyinbo nigba lailai ni ilu Oyinbo nma fi nsin ara wọn jẹ ati lati ma fi bu ara wọn, o si jẹ ohun ṣere-ṣere fun wọn, nigbati wọn si ko awọn enia wa ni ẹru lọ si ilu Aguda, awọn na, nigbati oluwa wọn ba fun won ni isimi ijọ meji tabi mẹta fun ere ọdun, iru ṣere-ṣere bayi a ma wa fun ọsan ati ohun miran bi iru eyi ti a npe ni ẹṣin Aguda *( Burinya )* ti ima jade loru pẹfu.

Awọn ti nwọn kọkọ da silẹ ni oko ẹru ti nwọn pada wa si ilu aiye tabi ilu Eko awọn na lo mu Kareta wa si Eko ti nwọn si ma nṣe ni akoko ọdun tirẹ.

Ni akoko lailai awon agbalagba ni ma nṣe Kareta, ti nwọn ba si jade lakoko ọdun wọnyi, ati ọmọde ati agbalagba lo nma jade lati wo iran wọn, orin wọn dun pupọ, bẹni wọn si mọ ijo jo pẹlu; awọn Mọmọyin a ma ba wọn wọ ode pẹlu, Pandero ni ilu ti nwọn fi njo, lọdọ wọn l'a si kọ gbọ pe Padero a nma powe—ati pe ilẹkẹ a nma ja towu-towu.

Awọn Kareta Ọkọnrin, ati Kareta Obinrin won a nma jo pade ara won, awọn Mọmoyin ti o nba wọn wọde ko si kẹrẹ lati ma ba wọn jo pẹlu, ko si ilu ti nwọn ki njo de, wọn a ma jo kakiri gbogbo Olowogbowo wọn si ma njo de ile wa pẹlu, bẹni wọn a si ma nri owo gba pupọ nile wa.

Nigbati o ṣe arẹ nmu awọn agbalagba ati gẹgẹ bi Owe ilẹ wa ti o wipe "Bi ina ba ku a fi eru boju bi ọgẹdẹ ba ku a fi ọmọ rẹ rọpo" bẹ l'ari lọdọ wọn pẹlu, nitori nwọn nfi ọmọ wọn ropo wọn diẹ-diẹ, ko pẹ lẹhin na, ere na di ti awọn ọmọde patapata.

Nigbati awọn agbalagba nṣe Kareta o ni ọwọ pupọ boju-boju wọn si dara pupọ, ẹnikanṣoṣo ni awọn fi ndi elekuru ti nwọn npe ni Epõ—bi awọn Kareta ṣere diẹ, Epo a bọ sinu ijo—Epo ti nwọn mọ jo pupọ—bi agbayun ti nma dun bẹni Kareta igbani nma dun loju gbogbo ilu.

Awọn agba Olowogbowo ko daba lati ba awọn Aguda ṣe Kareta titi wọn fi lo igba wọn koja pẹlu ara wọn, ṣugbọn nkan pupọ ni won nṣe ni Oketẹ nigana ti ara Olowogbowo ko gbọdọ de ipẹ lati ba wọn ṣe.

Awọn Aguda lo mu ijo bọlu *( Ball dancing )* wa si Eko, ẹnikẹni ko si gbọdọ ba wọn jo, wọn pe ijo na ni ti nwọn, ati ere ti nwọn lọ ṣe ni Oko Foresythe ti nwọn npe ni Bọn-fin ni akoko lailai, nigbati Oyinbo koi ti gba gbogbo ibẹ, alejo ti o ba ṣeṣi wo wọn, ana yira ni wọn nma na nwọn; gẹgẹ bi igbati Egun Tapa iba jade ọdun, eyi nikan l'o nma da ija silş larin awọn ara Olowogbowo ati ara Oke itẹ.

Nigbati Aguda ba gbe ẹṣin rẹ jade, ti nwọn ba le de Olowogbowo, awọn ara Olowogbowo a wa gbẹsan tiwọn lara wọn pada, nwọn a si gba ẹṣin wọn silẹ lọwọ wọn, Alagba Daddy Willoughby ti Oke Olowogbowo ni nma ranṣẹ si wọn (awọn Aguda) lati wa mu ẹṣin wọn; ko nṣe iru akoko ti nwọn nlo nisisiyi to jẹ pe nṣe ni nwọn nfi owo gba ohun ti nwon ba gba lọwọ ara wọn—Ṣereṣere ni awọn ti lailai ka si, ko si nşe ajaku akata bi iru eyiti nwọn nja lakoko yi.

Nigbati o wa di ti awon ọmọde patapata, ti awọn agbalagba gbogbo y'ọwọ kuro ninu rẹ, awọn ọmọ-wẹwẹ ti Olowogbowo lo kọkọ da Kareta tiwọn silẹ, ti nwọn si nfi ara we ti Aguda, a kọkọ njẹ igbadun wọn, ṣugbọn nigbati awọn ti Olowogbowo ṣere de itun Aguda, lati igbana ni wahala ti de, lati igbana ni ogun ti bẹrẹ, bẹni Kareta ko mu ija wa ni akoko lailai ni Eko yi, awọn ọmọ Aguda fẹran ija pupọ, awọn lo si nda ija nla yi silẹ, gẹgẹbi ọmọ ewurẹ meji ti nwọn yọ ayọ—"Iya mi l'a ra, a o ra mi." Bẹni awọn ọmọ Oke-itẹ nyọ lọrun-lọrun bi akọ pẹpẹiyẹ.

Gbogbo ilu lo ni ṣereṣere wọn, awon Fanti ni tiwọn, awọn Ṣẹkiri ni tiwọn, awọn Ijo ati Sobo ni tiwọn, Eko papa ni Iya-ilu tiwọn, gbogbo ara Eko lo si nba wọn jo, ati Sakara pẹlu ijo awọn ara Ilọrin, ti Karetr ha ti jẹ ẹnyin ọmọ Oke-itẹ—a ko ro pe awọn ọmọ Aguda papa ko jẹ kọ nibiti oju la de loni pe ki ẹnikẹni ma ba wọn ṣe Kareta mọ.

Sugbọn awọn ọmọ Oke-itẹ, awọn ọmọ Ọkanlawọn eleyin gangan, awọn ọmọ ti nwọn bi ti nwọn ko wẹ, awọn ọmọ alara yiyi bi ara agiliti, awọn ọmọ ti nwọn ge pako fun lati run ti nwọn fi jẹ bi ẹni j'ẹran bambam, awọn ọmọ ti ko mọ iyatọ larin ẹran ati igi, apọn'mọ wẹ, awọn afunja ma pon'mọ, awọn ọmọ ina, ọmọ Lafiaji, awọn ti ọmọ awọn Aguda ko bẹ l'ọwẹ, ti nwọn npe ara wọn ni nkan gunmọ—awọn ni nwọn ni ki ọmọ Olowogbowo ka ma ba awọn to ni **Kareta**, ṣe Kareta mọ.

Ilu ni lati ke pe Ijọba, akoko igbẹ sumọmi kọ la wa yi, ti awọn kan yio ma mnra ija wa adugbo miran, lati ja ati lati ṣe ṣuta, awọn abatẹnijẹ wọnyi ko mọ ofin, nwọn si nfẹ lati mu ara Olowogbowo ru ofin pẹlu wọn. Nitorina a o ma ke pe Ijọba ni igbagbogbo, ki o ma ba wa kilọ fun awọn ọmọ Jaguda wọnyi, ki nwọn jẹ ki awọn ọmọ-wẹwẹ ma ṣere wọn l'akoko ọdun o.

JALANKATO.


CHANGE OF NAME.

S. A. COLEMAN-DANIEL
TO
ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.

Commencing from the 1st day of February, 1928, the public are hereby notified that I, formerly known as S. A. Coleman-Daniel, do now desire to be known and called by the name

ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.

All documents bearing my former name remain valid

EKO AKETE

EKO, SATURDAY, JANUARY 21, 1928.

## EBI NP' EJO, AWUN NYAN!

A fi ilu Eko we ejo ti ebi npa, a si fi Ijọba we awun ti o nyan nipasẹ ọrọ owo-asingba ko ṣe owo-asingba ti o ti di rogbo-diyan larin awọn ilu, papa larin Ẹgbẹ Dẹmọ ati Ijọba: ko si oriṣiriṣi ọna ti a ko mũ gba pe ọmọ ti gbigba owo na yio bi yio jẹ ebi, inira ati hilahilo fun Eko ati igberiko rẹ; bi a si ti nsọ to yi, loju wa o dabi ẹnipe Ijọba nṣe "A ho o, A bẹntẹ, bi a ba ṣa ti ngba ṣa, kilo kan wa bi ebi pa ilu bi ko pa ilu, bi ara ni ilu bi ko ni ilu", ti o ba jẹ wipe ero bayi ni o mbẹ ninu Ijọba ni, njẹ irufẹ ọrọ bẹ ko se ọrọ Anikan-jopon lọ; Eko, ẹ ko ri oju aiye lode, owo-asingba koi ti di gbigba, awọn ile Oyinbo Onisowo meji mẹta ti ko 'gba sile ni igboro ilẹ yi, owo-asingba koi ti di gbigba, onile ọlọna nfi oru boju ntọrọ tọrọ, sisi kiri, owo-asingba koi ti di gbigba, gbajumọ miran nlọ fi orukọ olorukọ purọ gba owo ati ran ita, owo-asingba koi ti di gbigba, ọmọ onibi-niran di alairi 'ṣẹ ṣe, o nya 'jule jẹun kiri; owo-asingba koi ti di gbigba, ibajẹ owo le ọgọrọ ọmọluwabi lu 'ko bi Ọwawa; owo-asingba koi di gbigba, gbogbo ile Eko fẹrẹ di ti oni "wararo" agogo Gbanjo tan; owo-asingba koi di gbigba, ọgọrọ enia d'oku airi owo lo, atẹ ilẹkẹ d'atẹ ọrunla. Ha, ara Eko, igida, hun un un un!!! a bẹ Ijọba, a tun Ijọba bẹ pe ki nwọn sun ikaka ki nwọn si ronu pe "A ko gba", "A ko gba" ti ilu nke nisisiyi ki iṣe "A ko gba" ti Alaironu rara bikoṣe "A ko gba" ti inira nlanla ti owo-asingba bi irufẹ eyi yio mu wa lẹhin ọla; b'oku fẹ bi ko fẹ, ẹ ko ha ri ọmọ oloku lode, kakiri igberiko ti Ijọba ti lọ ba wọn sọrọ owo-asingba yi, oku sun danwo ni Warri ẹṣin fa titi o ku, enia rinrin o sọnu, tabi kilo tun ku.

Titaku na si sisan owo-asingba yi ki iṣe titaku afojudi, bikoṣe titaku ti gbigba ilu kuro lọwọ ohun ti o le tũ ka lẹhin ọla.

Ẹ jọwọ, ẹnyin Alaṣẹ Ijọba ekeji Oriṣa, ẹ masai gba ẹkun Eko sun lati dawọ ofin tulutulu yi duro.

Malu ti ko ni 'ru, Ọlọrun lo nle eṣinṣin fun u.

---

## AṢỌ ẸBI.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI JANAKU ]

Mo bẹrẹ f'oji

Nwọn ni bi ile ko dun bi igbẹ ni Ilu ri, nitorina bi a tilẹ sọrọ tamutamu ọrọ Ilu ni ọsẹ to kọja, iyẹn ko wipe ki a maṣe s'ọrọ lori nkan tabi aṣa buruku ti a mọ pe o ti ba alafia ọpọlọpọ jẹ lọwọ-lọwọ yi—Aṣa aṣọ ẹbi.

Kilo njẹ ẹbi bikoṣe ibatan, ọbakan tabi iyekan tabi anọ: nigbamiran a ma nka aladugbo ẹni si ẹbi ẹni, ti aladugbo na ko ba nṣe Kurumọ, tabi Hausa, tabi Oyinbo, tabi aladugbo buruku, tabi ara ilukilu miran ti ko si ohunkohun tabi ọnakọna ti o fi le jẹ oriki mọ wa.

Ọrẹ ni ọrẹ njẹ, bi o ti wu ki o le dun to; ṣugbọn a ko le fẹ ọrẹ miran ku ti o nṣika Ọmọluwabi fun ni ju ẹbi ẹni papa lọ. A ko le ṣẹṣẹ sọ pe iru ọrẹ ododo bẹ ti ni tikiti ti o le fi wọ ile ẹbi l'ọwọ.

Ti a ba mu awọn nwọnyi kuro, ko tun si ẹbi miran nibi kan mọ: ṣugbọn l'Eko, iba ṣe ole, tabi apania, tabi jandaku, eke, oniwa buburu gbogbo ti o ba si ti le ba wọn da aṣọ kanna lakoko iyawo tabi lakoko ijẹ miran ti nwọn le raye mu amupara ọti, nwọn ti di ẹbi ara wọn niyẹn, nwọn ti di iyekan, nwọn ti di ọbakan. Ti o ba tilẹ jaja jẹ panṣaga ni obinrin ti nkan kọn na, gbogbo ile a kun ṣọṣọ fun awọn Karuwa ati Dipọmu ẹgbẹ rẹ. Ibasi ṣe pe gbogbo awọn Karuwa ati dipomu yi ni ko si nile ọkọ, ṣe iba dun-dun. Ṣugbọn ãnu ṣe ni pe a nri obinrin alarede miran nibẹ pẹlu oruka lọwọ, lai ka ọgọrọ awọn to ri ẹni gbe wọn ni agbeda.

Gbogbo awọn to nda aṣọ ẹbi pọ nwọnyi, wọn ko ma ba ara wọn tan rara nidi iya tabi nidi baba ju ibatan nipa iṣekuṣe ati iwakiwa lọ.

Apẹrẹ buruku won yi si ngberan de ọdọ awọn enia atata tabi awọn ti a ka si bẹ tobẹ gẹ to ṣe pe bi obinrin to wa ni ọdẹdẹ ọkọ ba ni ki ọkọ da aṣọ ẹbi fun on tẹkini, tẹ eji, ti ọkọ ba kọ pe on tabi iyawo to fẹ da aṣọ yi ẹnikẹni ninu awọn mejeji ko ba oniyawo tabi ọmo oloku tan, ibinu de; iyawo rẹ le titori bẹ kọ ọ silẹ patapata, tabi ki o gbe ile rẹ di Karuwa, ki o ma di òpó alé mu lode nitori lati ri owo da aṣọ ẹbi. Nipa bayi, ọpọlọpọ ori

rere lo ti di ori buruku, alafia ọpọlọpọ Ile lo di alafiafia

Ni lọlọyi, a ri awọn oniyawo kan, awọn obinrin to da aṣọ ẹbi nibẹ, nwọn le ni adọjọ, ti nwọn nwọ lọ si i, bi ọkọ wete to fẹ doju de teni t'ọla. Baba lo mọ ọna ti olukuluku wọn fi da aṣọ tirẹ.

Ẹlomiran ra tirẹ lawin ti ẹlomiran ko jọ ole, ko jọ afọwọra, ẹlomiran nipa si sọ ara rẹ di Karuwa.

A ko wipe o buru fun ẹnikẹni lati ba ẹnikeji rẹ ṣe ẹyẹ pọ, agbẹdọ. Lati ba ara wa ṣe ẹyẹ lọna ti o tọ, ko si ohun ti o dara to, ṣugbọn iru ẹyẹ bayi, o buru, o b'ogiri. A sun ni sigbese ẹyẹ ni, a sọ ni di enia lasan ẹyẹ, matẹgbẹ ẹyẹ ni, ẹyẹ ki o dara l'owurọ, ki alẹ buru ni. Ọlọrun ki O jọwọ jẹ ki alẹ gbogbo wa dara ju owurọ lọ, *Amin*. Ṣugbọn a ni lati ṣe gbogbo nkan ni iwọntu wọnsi, a ni lati kiyesara, a ko ni lati ma fi ibajẹ ṣe ayọ.

Ọrọ wa lori aṣọ ẹbi yi koi tan rara, iyoku di igba miran lagbara Baba.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### The Annual Election of Officers of the Nigerian National Democratic Party.

The Committee meeting of the Nigerian National Democratic Party held at the Glover Memorial Hall on Thursday the 12th day of January, 1928, lasted from 5 p m. to 8.30 p.m., The Hon. Dr. Adeniyi-Jones, M.B., ( the Second Lagos Member ) was re-elected the President of the Party

The Hon. Dr. J. Akilade Caulcrick, M B, ( the Third Lagos Member ) a Vice-President of the Party was elected to succeed the late Hon Mr J Egerton Shyngle, B.L., as member of the Executive Committee.

The Hon. Mr. Eric O. Moore, B L. (the First Lagos Member ) a Vice-President of the Party.

Mr. T. Adebayo Doherty, B L, and Mr I. Kuṣika Roberts, B.L., were elected the Legal Advisers of the Party.

Mr. Phillips H. Williams was re-elected the Treasurer.

Mr. Thomas Horatio Jackson, Editor and Proprietor of the *Lagos Weekly Record*, remains as Honorary Secretary, having the Rev. J R. Williams, Pastor of the 1st Baptist Church, and Messrs. I. Ibaru and George I. Phillips as Assistant Secretaries of the Party, newly elected

Messrs. F G R Leigh, A O Cole, James Bailey, Lemọmu Lawani, Lemọmu Ọba (Okunu) and Musa Basorun, were elected as organising Secretaries.

H. Macaulay Esq., C.E., the Hon. E. O. Moore, B.L., Hon. Dr. C. C. Adeniyi-Jones, M.B., Hon. Dr. J. Akitade Caulcrick, M.B., Councillor J. Bagan Benjamin, C.E., A.M.I.E. C.E., and Thomas Horatio Jackson, Editor and Proprietor of the *Lagos Weekly Record* were elected as Executive Committee members of the Party.

Mr. T. Adebayọ Doherty, B L., a Vice-President, remains Secretary of the Board of Finance with his present Staff of Officers. Hats off to "Lord Derby."

### Arrival.

Mr. B. J. Reis, popularly known as Banadino, who was for about 22 years' resident at Duala, arrived Lagos last Friday the 13th January, 1928, by the French Steamer *S.S. Touareg*. Ẹ ka bọ.

### Candid Communications.

OUTSPOKEN MESSAGES TO CELEBRITIES NOTORITIES AND OCCASIONALLY NONENTITIES.

To Judge Whitmore Richards,
Chester Country Police Court.

Dear Sir.—When Sydney Husband Leavsley, a lad of nineteen, was charged with stealing three-penny worth of dry Bread because he was fatherless and motherless, homeless and starving, you considered it your "painful duty" to sentence him to four months' hard labour. I trust the home Office will consider it a pleasant duty to revise this sentence

---

To Sir Alfred Rawbinson,
Grosvenor Place, Westminster.

Dear Sir,—When summoned at Marylebone for driving without a motor-licence, it was stated that already you had been convicted seven times for this offence, and that you had been proved guilty of an enormous number of other motoring irregularities. In my opinion your stubborn disregard of the law amountss to deliberate contempt of Court and I trust you will not get off with a 40 shillings fine again.—*John Bull 10/12/27.*

### The Education [ Colony and Southern Provinces ] Ordinance. 1926.

*No 15 of 1926.*

Notice is hereby given that the Honourable the Administrator of the Colony, by virtue of the powers vested in him under section 7 (1) of the Education [ Colony and Southern Provinces ] Ordinance, 1926, has established a School Committee in the Colony, and appointed the following persons to be members thereof for a period of one year from the date of this notice.

The Administrator of the Colony, Chairman.
The Assistant Director of the Medical Service, Lagos.
The District Officer. The Colony.
The Superintendent of Education Lagos.
The Right Rev. Bishop Melville Jones.
The Right Rev. Bishop Terrien.
The Rev. O J. Griffin.
Mrs. Alice M. Duval.
Mr. P J C. Thomas.
The Rev. G. A. Oke.
The Rev. W. B. Euba.
Mr. J. G. Kuye. Ebute Metta.
Mr. L. B. Agusto.

*The Nigeria Gazette, 12/1/28.*

### Marriage.

A native marriage took place at 12, Babani Street, Ebute Meta. between Rev. J. F. Ogunko and Mrs. Sarian Atitebi, [ widow ], on Thursday the 12th January, 1928, at 7.30 p.m.

We wish the husband and wife all connubial bliss.

### On Leave.

Mr. E. Ọlakunbi Oke, Foreman Printer, Railway Press Ebute Meta, is on 2 months' leave, as from the 26th January 1928.

**Mr. Oke hopes to visit Ibadan to see his father, the Hon. Mr. E. H. Oke, Member for Ọyọ Division.**

**OLUŞAKIN.**

## IROHIN KUKURU TI ẸGBẸ "DẸMỌ" TI A ŞE NI ILE AFARI OGUN, NI IJỌ KẸRINLA OŞU JANUARY, 1928.

Ipade yi bẹrẹ ni nkan agogo mẹrin kọja diẹ nigbati Ọlọla Dokita Caulcrick bọ scri aga, awọn Oloye onifila funfun bi Olumẹgbọn, Eletu, Oluwa, ati Abagbọn, Cshodi wa lẹhin rẹ, ati awọn Ikomọ Ẹgbẹ.

Alaga pe Ọgbẹni Macauley lati sọrọ lori ohun kinni ti a fẹ şe, eyini ni, nipa Iwe Ẹbẹ ti a fẹ kọ si Gomina, nipa ti ofin "Tunaşiri." "Income Tax Bill."

Ọgbẹni Macauley wa yọ iwe ẹbẹ yi, o fihan gbogbo Egbẹ, o ni şugbọn ki o un to ka a, on yio la idi ohun ti a nbẹbẹ fun. Iru ofin ti Ijọba fẹ mu wa yi, ni ilu wọn papa ti ilaju ti de bẹ lati bi o le ni Ẹdẹgbẹta Ọdun, ko i ju Ogun ọdun lọ ti nwọn sọ di ofin papa, ni akoko ti Gẹsi ati awọn Faranse nba ara wọn ja (nwọn ma dẹ ti di ọrẹ şẹnyin o) ni oşelu wọn kan ti orukọ rẹ njẹ Pitt, on lo pe awọn Olowo jọ, o ni ogun yi nle, owo ko si si, Ijọba si nfẹ owo, nitori inawo ogun yi ti pọ, o wa sọ fun wọn pe, owo yin gbogbo ti a wa ni Bank, o un ko ni f'ọwọ kan, a mọ, ẹ o ma san Pọun kan lori ọgọrun ti ẹ ba fi si Bank, gbogbo wọn gba pe, o dara, lẹhin ti ogun pari ti Ijọba Gẹsi ti şẹgun, awọn Olowo wa sọ fun Ijọba pe ẹ ko ha ni ye owo yi gba wayi, şugbọn Ọgbẹni Pitt ni, ogun pari nitotọ, şugbọn o ku inawo ogun, nigbati o şe, o da duro, nwọn ko san mọ.

L'akoko ti Ọgbẹni Robert Peal tun bọ si ipo Pitt, o un na tun pe awọn Olowo jọ pe, ko si owo l'apo Ijọba, iru owo ti Ọgbẹni Pitt gba l'ọwọ wọn, o un na fẹ gba iru rẹ, nwọn si jẹ ọhẹn fun, iyẹn na tun gba bẹ, nigbati o şe, nwon tun da duro; o le ni ogorun ọdun ti nwọn fi ngba ti nwọn ndaduro, ki o to wa di ofin papa niwọn ogun ọdun sẹhin. Ilaju ti wa nisisiyi ko i to ọgọrun ọdun, ni nwọn ni ki a wa gba iru ofin yi. Ni ilu oyinbo papa lọhun, awọn ti o ni ilẹ nke şe ofin yi nni wọn lara, nitori lori Pọun kan ti o nwo'le fun wọn, eyiti o mbọ si apo Ijọba jẹ şile mọkand logun ati kọbọ mẹjọ; kẹbọ mẹrin pere ni awọn onilẹ papa nri na ninu rẹ, eyi mu ki ọpọlọpọ bẹrẹ si ta ilẹ ati irandiran rẹ; titi ọsẹ meji l'agbara Olọrun, a o tẹ orukọ awọn Idẹjọ (Duke) nwọnyi ti o ti bẹrẹ si şe eyi ti a wi yi sinu iwe irohin.

Nisisiyi Ijọba ni Pọun kan la o ma san lori ọgọrun pọun, nitoripe nwọn fẹ şẹşẹ bẹrẹ ni, tani le sọ iye ti yio da ni ọdun mẹwa oni, ẹ wo owo ti a nsan fun Bicycle, nigba kan ri, şe şile meji abọ ni, nisisiyi nkọ, o ti di şile mẹwa, Motor Car ti o jẹ pe ni ogun ọdun ọhun, owo ti mo san fun Municipal ko to Pọun meji, nisisiyi Pọun mẹfa ni l'ọdun, o jẹ ilọpo mẹfa, eyiyi ko ha nfi han ni pe, ofin yi ko jẹ ohun ti o le dara fun ni, papa nigbati owo ngbin kin l'apo Ijọba Iwe ẹbẹ ti a kọ yi, a ko fi ta Ijọba laiya, şugbọn, a nbẹ nwọn ni, nitori ko si ilu ti nwọn yio gbe nkan yi de, ti nwọn ko ni bẹrẹ si fi ibọn pania, eyiyi ni a si nsa fun nibi, nitori awa ko fẹ itajẹ enia silẹ ni ilu wa.

Itajẹsilẹ yi ni Ọba Dosunmu sa fun nijelo ti o fi fi ọwọ s'iwe adehun pẹlu Ijọba Gẹsi (ẹniti o ba nsọ pe Dosunmu gbe'lu ta nsọ aşisọ ni) nigbati nwọn o fi fa asia, awọn Şọja inu Ọkọ Ogun ni nwọn fi yi Iga ka ti nwọn ni awọn fun Ọba Dosunmu ni wakati mẹfa ki o şe eyi ti yio şe, nigbati Ọba Dosunmu ro o titi lo ba ranşẹ si Alufa Gollmer pe ki o ba o un sọ fun wọn pe o un yio fa asia s'oke nitori o un ko fẹ itajẹ silẹ, lẹhin ti nwọn fa asia ni August 1861, oşu mẹfa lẹhin na, ni nwọn to wa şe iwe adehun.

Ninu iwe ẹbẹ ti a kọ yi, a fihan Ijọba pe, nwọn ni awa ko nsan "direct tax" owo ile ti a nsan nkọ, eyiti awọn npe ni owo omi, owo (Improvement Rates) titi ti a nsan nkọ, mejeji jẹ Pọun mẹwa lori Ọgọrun Pọun, iru owo ti nwọn nsan ni ilu Gambari, iyẹn jẹ işẹdalẹ wọn, nitori lailai ni Fulani ti şẹgun wọn, ti nwọn si ngba owo ori lọwọ awọn Gambari. Ni Abẹokuta owo ibode ni nwọn ti ngba nibẹ ti Gomina Macgregor si şe atilẹhin pupọ fun wọn nipa rẹ, şugbọn nigba ogun ajakaiye ti Ọti ko wọ ilu mọ, ti Ijọba Ẹgba ko ri owo Ibode şe'lu mọ, ni nwọn ba da owo ori silẹ, eyiti o mu iku Ọşilẹ wa ti awọn Şoja Ijọba si pa bi Ẹgbẹdogun ọmọ Ẹgba si, nitori a ti kọ wọn bi a ti şe wa owo si apo Ijọba.

Ni ilu tiwa nihin, Ọba Dosunmu owo Ibode lo ngba Pọun meji lori Ọgọrun Pọun lori ọja ti o njade lọ, ati Pọun mẹta lori Ọgorun Pọun, lori ọja ti o nwọle, eyiti Ijọba sọ di Pọun mẹdogun lori Ọgọrun Pọun nisisiyi, lori ọja ti o nwọle.

Iru owo sisan ti ko şe tara (Indirect Tax) eyini ni owo Ibode ti a nsan yi, iyẹn ni a mọ nihin, eyiti nwọn si nfẹ mu wa yi, ki işe aşa wa rara.

Papa wayi o, ki a tilẹ ni a ni lati sanwo yi, nile nilẹrẹ, awọn ti o ba sanwo ni o ni lati ma tọju rẹ, şugbọn ni tiwa nkọ, enia mẹta pere ni nwọn fun wa laye ati yan larin Oyinbo bi mẹdọgbọn ti Ijọba ti nwọn nna owo yi kula, nwọn tilẹ na titi ko tan nibẹ, eyiti o ku papa ogidinleje ni, sibẹsibẹ nwon tun ni ki a tun wa bẹrẹ si owo miran lati san; nwọn tilẹ fẹ fihan wa pe, awọn ni Oluwa wa şa ni, gbogbo ọro yi gba a ni a la sinu iwe ẹbẹ yi, lati fi şowọ si Gomina fun Ọga ti ilu Oyinbo l'ọhun, Olodumare ki o si jọwọ tẹlẹ de wa nibẹ

Iwe ẹbẹ yi awọn ti nwọn ba gbe de ọdọ rẹ lati f'ọwọ si i, ẹniti o ba fẹ ki o fi ọwọ si, ẹniti ko ba si ię kẹ ti o ba ka a tan, ki o ma şe fi ọwọ si i. Lẹhin ọrọ nwọnyi, Alaga wa bere lọwọ gbogbo Ẹgbẹ pe ki nwọn fun awọn Ikomọ l'aşẹ ati fi iwe ẹbẹ yi ranşẹ si awọn enia lati fi ọwọ si i, ki a si fi ranşẹ si Ọga awọn Gomina ni ilu oyinbo lati ọwọ Gomina, gbogbo ọmọ Ẹgbẹ si na'wọ s'oke, Alaga tun bere pe awọn ti ko ba fẹ ki nwọn na'wọ s'oke, ko si ẹnikan ti o na'wọ, Ọgbẹni Alẹşinlọyẹ lo şe gbedegbẹyọ fun alaga.

Alaga tun wa pe Ọgbẹni Makọli lati sorọ lori ọrọ keji ti a bawa eyi i ni lati yan Ikọ ti yio mu iwe ẹbẹ na lọ si ọdọ Gomina, Ọgbẹni Makọli wa la a pe, ni Komiti ti a şe kọja, awọn ikomọ fi aşẹ si pe, ki a yan enia bi ti igba ti a lọ si ọdọ Ọgbẹui Ormsby Gore nijelo, enia meji meji ninu oniruru igun Eko, bi Onifila funfun meji, Abagbọn meji, Aguda meji, Asarudini meji, Komiti meji, Aşoju wa ni igbimọ mẹtẹta; ẹ o şe iranti pe awọn Oloye ko le ba wa lọ niti Ormsby Gore, nitoripe nigbati a fi oruko awọn ti a yan şọwọ, Lieut Governor ranşẹ pe Akowe wa ọgbẹni Jackson pe, ko dara ki awọn Oloye wa nitori agbalagba ni nwọn jẹ, wọn ko si gb'oyinbo, şe nkan ti aba sọ, a o lọ rohin rẹ fun wọn, eyi ni ko jẹ ki a le mu wọn lọ nigbana.

Alaga wa tun bere bi gbogbo ọmọ Ẹgbẹ gba eto ti awọn Komiti şe lati ran Ikọ lọ si ọdọ Gomina, gbogbo wa si n'ọwọ s'oke pe a gba.

Larin eyi ni Ọgbẹni Moore wọ ile, atẹwọ si ho ku u, o ki awọn Oloye, o si bọ s'ori aga, Dokita Çaulcrick kuro nibẹ fun.

Alaga pe Ọgbẹni Makọli lati wa sọrọ lori ti awọn Abọ ti nwọn ko ju s'ẹwọn, ati awọn ti nwọn wa lọ. Ọgbẹni wa tun t'ẹnu b'ọrọ, o sọ bi o ti jẹ pe nigbati District Officer lọ si Aboh lọ sọ fun wọn pe owo ori de, nwọn si ni lati san, ọkan ninu awọn ti a pe si apejo yi wa la ọna mẹsan silẹ ti awọn ko fi le ri owo san'wo ori. (1) Bi awọn gegi ọpẹ tabi iroko, Ijọba a gb'owo. (2) Bi awọn kan ọkọ nla tabi kekere, awọn a sanwo. (3) Bi obinrin fi ọkọ silẹ, ti ọkọ lọ p'ẹjọ owo bi pọun marun lo tun nbọ s'apo Ijọba ninu iyẹn. (4) Bi aya gb'ọkọ l'oju ninu ile ti o si yara şaju lọ sọ ni Bareke pe ọkọ lu oun, owo sisan de (5) Oşu mẹta ninu ọdun kan ni awọn fi nsin fun işẹ ọna Mọto lai gba okan lọwọ Ijọba. (6) Ẹru igi meji l'oşu ni awọn ọdọmọknurin nwọn nru l'ọfẹ lọ si Bareke lai san okan fun wọn. (7) Ọfẹ ni awọn nru ẹru fun Ijọba lọ si irin ajo ti o jẹ pe o ngba ijọ mẹta ki awọn to bọ. (8) Ọna Mọto awọn la nla nigba ti o ba ya lọ si bi ilu meji iaigba kọbọ. (9) Ọsọsẹ ni nwọn nko awọn aya wọn lọ pa'lo awọn Kotuma (*Court messengers*) ati awọn akọwe Kotu lai si epinni; nigbati awọn nşe gbogbo işe wọnyi lai gba owo lọwọ Ijọba, nibọ ni awọn ti mẹ ri owo lati wa fi san şile mẹwa o, nibiti nwọn gba wa ninu apejọ yi ni nwọn ba ni ki awọn Ọlọpa me Oloye wọn, wipe on lo nkọ wọn pe ki nwọn mu sanwo. Oloye Odua yi, nwọn ju s'ẹwọn, ati ọpọlọpọ ninu awọn agbalagba ibẹ ati awọn obinrin pẹlu. Ọba ilu na papa ti o ti lọ gba lọdọ awọn Oyinbo ri gbangba pe ilu kọ ati san owo-ori, o wa lọ sọ fun D.O. pe nwọn nkọrin bu on kiri, nwọn wa mu olori awọn obinrin ilu na, ni ijọ mẹjọ-mẹjọ, nwọn a lo fọ ẹyin adiẹ lori rẹ larin ọja; nigbati awọn ara ilu ri iwa ti nwọn fi nhu awọn enia wọn, nwọn ran enia meji lati wa si Eko fun Agbẹjọro ti yio ba wọn kọ iwe, Ọba ilu wọn tun ranşẹ lati lọ mu wọn bọ, ni ikan ninu wọn ba sa si igbo, boya nwọn de'lẹ yi şa. Ẹ o şe 'ranti pe awọn ara ilu wọnyi gbogbo lo şe iwe-ẹbẹ si Igbimọ nijelo, nipa ọrọ owo-ori yi, şugbọn ti Adele Ọba Baddeley ni nwon ko gbọdọ ka. Iwe-ẹbẹ wọn na, a o fi sinu tiwa pẹlu, o ta si mi leti laipẹ yi pe nwọn sọ fun Gomina pe awọn ara Warri ati agbegbe rẹ gbe owo wa fun mi, lo jẹ ki nma sọrọ nipa wọn, ẹniti o ba mọ ara Warri ti o gb'owo wa. ki o jọwọ ki o maşai dari wọn si mi, nitori nkoi ti ri kọbọ kan pere, enia ha le duro ki o r'owo ki o to ja fun ilu rẹ ni ọna bayi. emi ko wa iru owo yi ki nto sọ ohun ti ng o sọ, ni idi otọ ngo kọ lati fi ẹmi mi şe (gbogbo enia ni o ti, o ti, ka ma ri i). Bi nwọn ba fẹ, ma fi aye fun wọn lati jẹ ki Ọlọpa inu ma wa sun ninu ile mi lati ri bi ẹnikẹni gb'owo wa si ibẹ. Bi awọn enia wọnyi ti ma nşi Ijọba lọna ni nwọnyi, bẹni nipa ọran Eşugbayi Eleko, nwọn ni awọn ti f'ẹsẹ tẹ pa, Makọli nikan lo kan nsọ nkan to wu, ilu ko bere nipa rẹ, ọran ti nwọn f'ẹsẹ tẹ na lo wa nilu Ọba nisisiyi, ti Lọya ti Eleko ti mura tan, ti Lọya tiwọn koi t'ode bọsi. Bi o ba jẹ pe Lọya wọn ti dahun ni, ijọ kọkanla oşu yi ni nwọn ba fi pẹki ko pẹki, şugbọn a tun ri ka ninu iwe-irohin *West Africa* pe titi oşu *March*, nwọn a fọn si ẹjọ na. Mo tọrọ gafara lọwọ Alaga lati ya si ọran ti Eleko, şngbọn ohun ti o jo'ra wọn la fi nwe 'ra wọn. Gbogbo ọrọ wọnyi la o fi han Gomina patapata, ti a o si la fun yekeyeke. Ọlọrun ki o jare ki o maşai tẹlẹ de wa lọhun.

Owo ti a nsan nisisiyi nipa ibiti a npe si yi, o pọju, pọnun mẹjọ, nitorina a o bẹ Ọgbẹni wa Ọlọla Moore (nitori o jẹ ọkan ninu awọn alabojuto nisisiyi) lati ba wa so fun awọn ti o nşe itọju ibi yi pe ki nwọn din owo na ku, ki a le raye ma pade laseko ti o tọ, ti o yẹ.

Lẹhin ti Ogbẹni Makọli sọrọ ni Alaga wa dupẹ lọwọ ọmọ Ẹgbẹ fun wiwa ti nwọn wa, o si mu ẹnu kan ọran ti owo ti a nsan fun ibi ipade eyiti Ọgbẹni Makọli sọ, o ni on a gbidanwo lati ri pe nwọn din ku, nitoripe o wọn ju, pọun mẹjọ, bẹni owo ti a ti nsan ri ko ju şile mẹrinlelogun lọ. O ni on ko şeleri pe bẹ gan ni yio ri, şugbọn on a sa ipa lati ri pe o jẹ bẹ, nitori oun jẹ ọkan ninu

awọn ti a yan lati ma ṣe itọju Ile Afari Ogun nisisiyi.

Lẹhin eyi o pari Ipade niwọn agogo meje nlọ lu.

FANOKUN.

ORI II.

## IWA—AGBARA TI ẸKỌ ILE NI.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KEJE.

Gretry, alarofọ-orin *(musical composer)* gba pe obinrin gẹgẹbi olukọni-ni-iwa, jẹ ọranyan tobẹ ti o fi sọ pe iya rere jẹ "Ẹda ti o dara ju laiye,"

Bẹ ni o ri: nitoripe awọn iya rere (ti baba ko to nkan) ni ki idẹkun lati tun aiye ṣe, gẹgẹbi afẹfẹ ti iṣe ọ'ọ̀jọ ara enia bẹni iwa rere iya nṣe ọlọ̀jọ iwa enia. Nipa suru ati inu rere lọna ọgbọn, obinrin a fi idunnu, itẹlọrun ati alafia ka gbogbo awọn ara ile, eyiti imu enia ni iwa rere.

Ile akuṣẹ le jẹ ibiti itura, iwa rere ati idunnu wa, bi o ba ṣe pe iya ile na ba fi iwà mimọ, aina inakuna, inu rere ati imọ-toto tọju ile rẹ.

*Translated By*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

## The Editor's Observatory.

A RECORD DEBATE.

The members of the Study Circle treated the public to a record debate in the Committee Room of the Glover Memorial Hall in the evening of Monday last under the Chairmanship of His Honour Justice M. L. Tew, when the subject

"Whether Sir Elijah Impeh, the Learned Chief Justice of India was justified in sentencing Nuncomer to death"

was ably handled by both the Pro and Con side; after preliminary remarks the Chairman; Mr. G. D. Francis, who was followed by his supporters, as Leader of the "Pro" side, opened the debate in a long but reasoned speech, whilst Mr. S. Akisanya with his retinue, as Leader of the Opposition rebutted the Pro's arguments in a telling speech: at last the Noes won the "toss", and Mr. Justice Tew promised to forward his Judgment to the Circle in writing

There was a packed house; needless to say, that His Honour controlled the destny of the evening with characteristic coolness.

Floreat, the Study Circle.

## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣe ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti ko ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ ma gbẹhin, ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.


Disinfectant Soap of Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap Tablets
MAGNET
SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## White's Golden Male Tonic

(DOUBLE STRENGTH)

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.* - NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nkan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Paintull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WOND RFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the b in such a way, that the regular user is able to many times the usual amount of Brainwork he used to do, before using it. To Brainwor and those who have examinations to pass, it boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE,
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer.

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy Insufficiency or Loss of the monthly courses Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

***Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.***

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undertaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is **Solicited.**

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Y[illegible]
ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to[illegible]
si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ b[illegible]
awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami s[illegible]
ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn

Pọ ọ si ni owo wọn.



PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.